ỌN OHUN PATAKI NINU IWE ỌSE YI
Adeniran d'eni Ọrun
Oju iwe 1
Adelusi Faṣọrọ di ologbe
Oju iwe 1
Ipade Akakọ ni Itagun
Oju iwe 2
Fi orukọ silẹ fun idibo
Oju iwe 3

# IRAWỌ ★ OBOKUN

Ọpẹsiyi Avọura d'ologbe
Oju iwe 4
Ran Irawọ Obokun lọwọ
Oju iwe 5
Ipade Ijẹṣa ni Oke-Ọya
Oju iwe 5
Ero ṣọ bere l'Oke-Ọya
Oju iwe 7
Fala gb ọ tirẹ
Oju iwe 8

Vol 4 No. 160 ILESHA MONDAY OCTOBER 31 1955 IYE OWO: TỌRỌ

# ABURO BABA SAMUEL ADENIRAN KU LẸHIN ỌJỌ KẸTA TI ON TIKU

## ADENIRAN AROMỌLARAN D'ẸNI ỌRUN

Ni owurọ kutu ọjọ karundọgbọn oṣu yi ni okiki kan yi igboro Ilẹṣa ati agbegbe ka wipe Ọmọba Samuel Adeniran Aromọlaran ku.

Ọpọlọpọ lo bẹrẹ si i ṣe ariyanjiyan nitoripe wọn ni o lọ si ipade Ọlọpẹ lọjọ kẹrinlelogun oṣu yi, o si si ipade idile Ọba nibiti wọn ti lọ pitan nipa bi wọn tiṣe nṣẹ Ọba ni ilẹ Ijẹṣa.

Tori ariyanjiyan wọnyi ni ọpọ ero bẹrẹ si wọ lọ si orita Iṣokun ladugbo Ọmọba na lati mọ otitọ. Ọpọlọpọ ara adugbo Ọrikiran lo sọ pe awọn ri Ọmọba na ni nkan bi agogo marun irọlẹ ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.

Wọn ni kosi ẹniti o le ro iku si Ọmọba na titi di nkan bi agogo mẹjọ alẹ ọjọ na lati igbati ko le sọrọ si ẹnikẹni mọ titi o fi lọ jẹ ipe Oluwa.

Lati ọjọ to tiku si ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi ti wọn sin oku rẹ, kosi wakati kan ti orita Iṣokun ṣe alaikun fun ogunlọgọ awọn alabakẹdun.

Ọpọlọpọ awọn ọmọ, ebi, ibatan, ọrẹ ati awọn Ọmọba ilẹ Ijẹṣa lo ti bẹrẹ si i de nitori isinku rẹ. Ni dede agogo mẹta ọsan ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi ni ogunlọgọ ero tẹle oku rẹ lati ile rẹ ni Iṣokun lọ si ile ijọsin ti Methodist ni Ọtapẹtẹ.

Awọn Scout, Brigade ati awọn Girls' Guild pẹlu awọn ọmọ ile iwe Grammar School, ati ti ile iwe giga Obirin Methodist ati ti Ọtapẹtẹ lo ṣaju kẹkẹ oku na pẹlu orin aro. Wọn gbe oku na gba Orikiran kọja ni ọja lọ si Ọtapẹtẹ.

Ki wọn to de Ọtapẹtẹ, ile ijọsin ti kun ko gba ẹsẹ mọ. Pẹlu agbara niwọn fi gbe oku wọle.

Lẹhin ọpọlọpọ orin ati adura ni Eni Ọwọ N. O Salakọ ṣe iwasu fun odindi iṣẹju mejilelọgbọn. Ohun to fiṣe akori iwasu na ni "Ma dupẹ fun ohun gbogbo." Lẹhin iwasu na to kun fun ọrọ iwuri nipa igbesi aiye Samuel Adeniran Aromọlaran to di ologbe, ni wọn gbe oku na lọ si iboji.

Ki oku to jade ni ile ijọsin ni ero ti to lati ibẹ de iboji lọtun losi. Kẹkẹ tabi mọtọ kankan ko raye gba ibẹ kọja.

Eni Ọwọ Salakọ na lo ṣe isin isinku na ni iboji lọhun. Lẹhin isin na ni olukuluku pada sile ni nkan bi agogo mẹfa abọ irọlẹ.

## IKU ORO TI ṢE TỌ SI OLỌDODO?
(Lati ọwọ Ọgbẹni S. Akindele Ojo)

A ṣe e, bi siẹ ti nṣẹ, ti oju nmọ, ti olukuluku nghe ẹsẹ, ni olukuluku ntun mọ ọjọ iku rẹ. Daju emi mọ pe o pẹ ni, o ya ni, dandan a ni lati ku. Ṣugbọn tani eni na to je rope Olododo le ku iku oro? Tani eni na to je ro pe iku oro tọ si olododo?

Ko si ẹniti o jẹ ro bẹ, lotọ iku oro ko tọ si olododo, a fi ibiti itọju emi olodo na ti wa pi ikawọ Ala'biki[ia].

Ni irọlẹ ọjọ ọsẹ ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni nkan bi agogo mẹfa ni mo duro nibi enikan sọrọ ni ibiti adugbo lọọti ti jade si Okeṣa. Nibẹ ni mo ti ri Ọgbẹni Ọlajide Adelusi Faṣọrọ to jade ninu ile alagbeka (petesi) kan legbe ibiti wọn ti ntun mọtọ ṣe ladugbo na.

Bo ti jade, mo nwo ni ọkankan pẹlu aṣọ otutu (over coat) nla kan to fi kọ apa osi. Bo ti tinu akamọ ojade ile na bọ si oju ọna, mo ri ti o fi ẹsẹ kọ okuta lọkankan, ọkan mi sọ sofun mi pe oju lo nkan lati tele lọ ba mọtọ to ti nṣe iṣẹ akọwe to ti mura tan, to si ti nduro de lati lọ si Eko. Bo tide ọdọ wa, awa mejeji to duro ki, a si ti pe o fẹrọ ma ṣe akiyesi pe on fẹṣẹ kọ.

Lori irin ikanju, o sọ fun wa pe on nlọ si Eko, a si ki pe o dabọ.

Ni owurọ ọjọ keji, ni nkan bi agogo mọkanla abọ ni mo gbọ pe mọtọ Ijẹṣa kan ṣe jamba ni itosi Ṣagamu. Gbogbo ibi ni mo ti gbọ pe mọtọ ti Ọgbẹni Ọlajide Adelusi Faṣọrọ ti nṣe akọwe ni. Mo gbọ siwaju wipe on lo tilẹ farapa ju. Wọn ni o nwe labẹ itọju Dokita ni Ṣagamu, wọn ni wọn tun ti gbe lati ibẹ lọ si Eko.

Ki o to di ọwọ irọlẹ ọjọ na ni ọpọlọpọ awọn ọrẹ ti wọko o di Eko. Ni ọjọ keji ni irohin de lati ọdọ wọn pe Ọlajide ti gba ibẹ kọja si ọrun.

Ọrọ na ka ile lara to bẹ gẹ. Ọpọlọpọ obinrin alatẹ ọja ni ko

(Bere ni oju iwe 5)



ỌMỌ'BA SAMUEL ADENIRAN AROMỌLARAN
On ni aṣaju awọn Ọmọba Ilẹ Ijẹṣa, Ọkan ninu awọn aṣaju onisowo koko, Ọkan ninu aṣaju Ẹgbẹ Atunluje, Ọkan ninu awọn Eleto itọju Ilesha Grammar School. Laiṣe aisan titi alẹ igbati ọjọ iku rẹ dọla, o ku ni ọjọ karundọgbọn oṣu yi.

## AKANBI SỌ ỌMỌ LORUKỌ

Ni ọjọ ọsẹ ọjọ kẹtalelogun osu yi ni Ọgbẹni Akanbi ati iyawo rẹ Ajọkẹ sọ ọmọ wọn lorukọ ni 144 Ọrikiran Ilẹṣa.

Lati owurọ ọjọ na ni alabaṣẹyẹ wọn ti nde, ti olukuluku nse, ti wọn si nsọ. Igbati o fi ma to agogo mọkanla ọjọ na ile wọn ko gba ẹsẹ fun ọpọ ero.

Lẹhin ọpọlọpọ adura ni wọn sọ ọmọkurin na ni KAYỌDE AKANBI. Gẹgẹbi aṣa olukuluku lo nfi owo sinu omi ti wọn fi ngbadura fun ọmọ na, iya rẹ ati baba rẹ pẹlu awọn ẹgbọn rẹ.

Ki Ọlọrun wo ọmọ na ju wa lọ. Amin.

## IPADE IJOYE AGBEGBE D'ỌJỌ KARUN NOFẸMBA

Ipade ijoye agbegbe ti a ṣe ni Iwo lọjọ kẹdogun oṣu yi ko kun to bẹẹ. Nitorina awọ aṣoju fun gbogbo ijoye agbegbe ninu Igbimọ gbogbo gbo o ko le ṣe irohin ipade to kọja fun awọn to wa lọjọ na.

Nitorina a tun pe ipade miran si ile iwe Africa ni Aragan ni Ilẹṣa lọjọ karun oṣu kọkanla ọdun yi. lagogo mẹwa owurọ.

A si fẹ ki gbogbo awọn Ijoye agbegbe wa si ipade lọjọ na lagogo mẹwa owurọ lati wa gbọ ẹkurẹrẹ irohin lẹnu Aloko ti Ileko ati Lọja Iṣiregun.

**WANTED.**

**ONE Exprienced Clerical Assistant with a rudimentary knowledge of simple business accounting.**

**One experienced Printer and Book-Binder.**

**Applicants to appear in person within a week at the Workshop of the Ijesha Press Ltd., B 149 Okesha St., Ilesha.**

# IRỌHIN LATI AGBEGBE

## IBODI NFẸ IRANLỌWỌ ỌLỌPA INU
(Lati Ọwọ Ọmọ Ibodi)

Yio dun mọ mi ninu bi ẹ ba le gba mi laye lati fi ọrọ mi yi sinu iwe rẹ oloyin mọmọ ti ọsẹ yi· Lati nkan bi oṣu kan gbako ni irohin ti nde etigbọ wa wipe awọn ole nyọ awọn ara ilu wa yi lẹnu, papa julọ ni ọjọjọ marun ti nṣe ọjọ ọja ilu yi. Ko si si awọn miran to nṣe nkan wonyi lẹhin awọn Hausa, ati wipe awọn agba a ma pa lowe wipe bi ina ko ba lawọ ki goke odo.

Ki a to le wadi nkan wonyi finifini yio lodi ṣofin ijọba lati ṣe fun ara wa. Nitori eyi yio dun mọ ọmọde aa agba ninu bi awọn ọlop ọtẹlẹ muyẹ, awọn ti a npe ni C I D ba le bani ṣe iwadi iru awọn bawọn yi lati fun ilu yi ni alafia ki wọn ma ba sọ ọja ilu yi di igbo aiwọ fun ọpọlọpọ enia.

Irohin tilẹ nde etigbọ wa wipe ọpọlọpọ ninu awọn ti awọn enia funra si fun iru iṣẹ ibi bawọn yi pe ọpọlọpọ ngbe ninu ilu yi.

A fẹ amojuto awọn ọlọpa lori eyi onilu ko fẹ ko tu,

A dupẹ Olotu. Obokun a gbe yin o.

## KINI AWỌN ARA IJẸMBA ṢE?
(Lati Ọwọ Isaac Ade. Apantaku)

Mo ki Olotu Irawọ Obokun ati awọn oṣiṣẹ re pe ẹ ku iṣẹ ati iṣeto Mo si tun dupẹ lọwọ nyn nipa jijẹ ki olukuluku leri aye lati ma sọ ọdan ọkan re fun ijọba ati pe o si njẹ ki olukuluku le ma gbọ gbogbo ọrọ nipa eto ilu ni ilẹ Ijẹṣa

Ina mi yio dun ti ẹ ba le fun mi ni aye lati sọ iba ọrọ diẹ ti mo fẹ sọ nipa ileto kan ti a npe ni Ijẹmba ti o jẹ ereko kan pataki ni ilu Ilesa. O ti to iwọn bi ọgbọn ọdun sẹhin ti awọn ara ilu yi, ti nnawo ti wọn si nna ra leri ọna ti o jẹ maili mẹrin; Ọdọdun si ni wọn nfi tẹdun tẹdun fi ọrọ leri oju ọna yi siwaju Ijọba, ṣugbọn ko si iranlọwọ kankan ti wọn nṣe ti a ri lati fi ran wa lọwọ. O si wa jọ ni loju nigbati wọn ṣe gbogbo eto leri oju ọna ti wọn fi oju ọna ti wa da lai ṣe ni ọdun yi.

Nitorina a bẹ awọn oluṣeto ti o nṣeto leri ọna kiwọn ma sai jọwọ fi ẹsọ wa tabi ẹsun wa sinu iwe Irawọ Obokun, ohun ti o mu ki wọn ṣe eto leri ṣiṣe oju ọna gbogbo ti wọn ko fi ṣe tiwa.

Ohun kan pataki ti o dun ni ju ni ti awọn ọmọ ile-iwe ti o nrin ọna yi ni nkan bi maili meji si leto na.

Ni araro ki awọn ọmọ ile-iwe o nlọ si ile iwe ni Ijẹmba lati gbegbe to de ile iwe wọn, aṣọ wọn tirẹ jingbindin, gbogbo rẹ a

ri jaunjaun, awọn papa a si wa da bi olukuburun etutu a ti wa bo omiran ninu wọn ti yio si bẹrẹ si gọvn oi ewe ọbọ.

Bi wọn ba rọju titi orun yio fi la nigba miran, ti aṣọ wọn si gbẹ ki wọn to jade ni igba miran, ti ojo ba si tun ti rọ, ṣibati wọn ba tun fi ma pada de aba wọn gbogbo aṣọ wọn a tirẹ jingbindin, nitori ọna yi ko ṣe fi ẹsẹ rin mọ ka ma ṣọṣẹ sọ wipe ti moṭọ

Ko si aye lati ko gbogbo eso wa ti o wa ni oko wa sile.

Ko si si ọna lati lọ ma ra ohun jijẹ lati ọja wa nitori ọna yi urepọ, awọn ara ilu yi siti nṣẹ titi ti wọn siti sangbo sangbo, titi o fi su wọn.

Eyi wa mu ki o ye olukuluku ara ilu Ijẹmba ṣe iya ni o njẹ wọn leri ọna yi pẹlu pẹlu ohun to dun ni ju nibẹ niti awọn ọmọ ile iwe wa ti ko ri aye rin de inu ilu mọ.

Awa si wa bẹ ijọba tabi awọn alaṣẹ pe ki wọn ki o jọwọ ki nwọn ki o jẹ ki a mọ ẹṣẹ wa nipa kikọ jade ninu iwe irohin ti ọsẹ ti o mbọ.

Nitori awa ko mọ idi ti wọn fi ṣe eto gbogbo oju ọna ilu si o yi waka ti wọn fi awa nikan si arin igbo.

Nitorina awa fi eyi si iwaju nyin ẹnyin oluṣeto, idi rẹ ti ẹ fifi ọna ti wa silẹ lai ṣe, awa si nreti esi iwe yi sini ọsọ to mbọ.

## IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra Irawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogundele, Ọna Ẹfiọn No 644 Ẹrinmọ.

## FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.



ỌGBẸNI I O AJANAKU

On jẹ ọkan ninu awọn ana ti Ọmọ'ba S. A Adeniran to di Ologbe lọjọ karundọgbọn oṣu yi. Ogunlọgọ ero lo si ologbe na de itẹ. Lati igbati Ọmọ'ba na ti ku ni nwọn ti nki awọn ọmọ rẹ lọkunrin lobirin ku aṣẹhinde

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | OJU EWE KINI | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inşi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 7s. | ,, ,, ,, |
| | | OJU EWE KEJI | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun inşi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 4s. | ,, ,, ,, |
| | | OJU EWE KẸTA | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. ,, | ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | ,, ,, ,, |
| | | OJU EWE KẸJỌ | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inşi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | ,, ,, ,, |
| Igba | 26—52 | 5s. | ,, ,, ,, |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

